# IGBALA NIPA OORE-ỌFẸ

Nitori ẹyọ ẹsẹ kansoso ni a fi le awọn obi wa akọkọ Adamu ati Efa jade kuro ninu ọgba Edẹni. Bi o ba se wipe nitori ẹyọ ẹsẹ kan a le wọn jade kuro ninu paradise ti o wa lori ilẹ aiye o han kedere wipe ẹyọ ẹsẹ kansoso to lati ti ilẹkun Paradise ti Ọlọrun ti o wa ni Ọrun. O se, a ko jẹbi ẹyọ ẹsẹ kansoso, sugbọn ẹsẹ — ti o pọ ti o si ga bi oke — ẹsẹ nipa ero, nipa ọrọ, nipa ise, ẹsẹ ti a mọ, ati eyiti a ti gbagbe — ẹsẹ ni ikọkọ ati ni gbangba. Ranti wipe ko si ẹniti o le dari ẹsẹ ji eniyan bikose Ọlọrun nikansoso.

Bi o ba se wipe ẹlẹsẹ ni wa nigbanaa, ti ko le wọ ọrun, bawo ni a se le mu ẹsẹ wa kuro ti a o si ba Ọlọrun laja? Kini Iwọ le se lati se etutu fun ẹsẹ rẹ? Njẹ awọn ododo rẹ le mu ẹyọ ẹsẹ kan kuro? Tabi o lero wipe awọn adura rẹ, ati ọpọlọpọ ironupiwada rẹ, tabi adura awọn ọrẹ rẹ le mu awọn ẹsẹ rẹ kuro? Adura dara pupọ ni aye ti rẹ, bakanna ni ironupiwada, sugbon awọn nkan wọnyi ko le mu ẹsẹ rẹ kuro niwaju Ọlọrun rara, ko seese. Ẹjẹ Jesu Kristi nikansoso ni o le se eyini. Iwọ yiọ gba ẹkunrẹrẹ idariji l'ọfẹ nitori orukọ Jesu Kristi nigbati iwọ ba gbagbọ

ninu agbara Ẹjẹ Rẹ, gẹgẹ bi ohun naa, eyiti o ti mu ẹsẹ rẹ kuro patapata titi lai.

Iwọ sa fi eti silẹ si ohun ti Ọlọrun funra Rẹ sọ ninu Ọrọ Rẹ: "Gbogbo wa ti sina kirikiri bi agutan, olukuluku wa tẹle ọna ara rẹ, Oluwa si ti mu aisedeede gbogbo wa pade lara Rẹ" (Isaiah 53:6). "Ẹniti On tikara Rẹ fi ara Rẹ ru ẹsẹ wa lori igi" (1 Peteru 2:24). "Sugbọn nisisiyi li O fi ara han lẹẹkansoso li opin aiye lati mu ẹsẹ kuro nipa ebọ ara Rẹ" (Heberu 9:26). "Ẹniti . . . lẹhin ti O ti se iwẹnu ẹsẹ, O joko li ọwọ ọtun Ọlanla li oke" (Heberu 1:3). "On ni gbogbo awọn woli jẹri si pe nipa Orukọ Rẹ li ẹnikẹni ti o ba gba A gbọ, yio ri imukuro ẹsẹ gba" (Ise Aposteli 10:43). Ohun kan ti o nilati se ni wipe ki o gba ẹri Ọlọrun nipa irubọ Ọmọ Rẹ, ki o si jẹ ki ọkan rẹ simi le isẹ ti Kristi ti se pari. Iwo yio siri imukuro ẹsẹ rẹ gba, ki ise eyi nikan, bakanna iwo yio di Ọmọ Ọlọrun, iwọ yio si le maa yọ ninu ireti ogo Ọlọrun.

"Njẹ bi a si ti nda wa lare nipa igbagbọ, awa ni alafia lọdọ Ọlọrun nipa Oluwa wa Jesu Kristi: nipasẹ Ẹniti awa si ti ri ọna gba nipa igbagbọ si inu Oore-Ọfe yi ninu eyeti awa gbe duro, awa si nyọ ninu ireti ogo Ọlọrun . . . Notori igbati awa jẹ alailera li akoko ti oyẹ, Kristi ku fun awa alaiwa-bi-Ọlọrun" (Romu 5:1, 2, 6).

**Word Of Truth**, P.O. Box 1126, Kaduna, Nigeria